ONDO JOURNAL OF ARTS, 2 (1), 2026
Journal homepage: https://ojaafued.com/index.php/ojall
Recieved 20.11.2025, Revised 02.01.2026, Accepted 10.03.2026,
Published 30.04.2026
ISSN:1597-104X



# ÒWE YORÙBÁ GẸ́GẸ́ BI ÌPÍNṢÍṢỌ̀RÍ Ẹ̀YÀ LÍTÍRÉṢỌ̀ ALOHÙN YORÙBÁ

**SAADU Taofiq Ph.D.**

## Àṣamọ̀

*Àfojúsùn ìwádìí yìí ni àgbéyẹ̀wò òwe Yorùbá gẹ́gẹ́ bi ìpínṣíṣọ̀rí ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Iṣẹ́ yìí ṣe àkíyèsí pé, ọ̀pọ̀ ìwádìí tó wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ lórí òwe ni kò fi bẹ́ẹ̀ kọbi-ara sí ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá tí a lè ka wọ́n sí. Àwọn onímọ̀ kan kà òwe sí èròjà lásán fún ewì alohùn Yorùbá. Ìwádìí yì gbìyànjú láti dí àlàfo yìí nípa ṣíṣe àgbéyẹ̀wò òwe láti ṣàlàyé àbùdá àti ìpínsíṣọ̀rí rẹ̀ nínú lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Ìlànà ìṣèwádìí méjì ni a ṣe àmúlò nínú iṣẹ́ yìí; àkọ́kọ́ ni ṣíṣe àkójọpọ̀ òwe Yorùbá láti inú ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìmọ̀ ìgbé-ayé àwùjọ Yorùbá. Ọgbọ́n ìṣèwádìí kejì ni ṣíṣe àmúlò àwọn ìwé tí ó wúlò fún iṣẹ́ yìí, àwọn ìwé bíi, jọ́nà, átíkù àti orí ìtàkùn ayélujára. Àwọn àkójọ-èdè-fún-àyẹ̀wò yìí ni a fi tíọ́rì ìfìwádìí-sọ̀tumọ̀-ìṣẹ̀lẹ̀-àwùjọ (Sociological Hermeneutics) ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀. Ìdí pàtàkì tí a fi ṣe àmúlò tíọ́rì yìí ni láti wo ìwúlò òwe pẹ̀lú iṣẹ́ tí wọ́n ń fi wọ́n ṣe nínú àgbékalẹ̀ ìhun àwùjọ. Àbájáde ìwádìí yìí fi hàn pé iṣẹ́ tí òwe ń ṣe ní àwùjọ Yorùbá kò kéré rárá, àtipé, bí a bá wo àbùdá òwe Yorùbá a ó rí i pé ó kọjá èròjà fún ẹ̀yà ewì alohùn Yorùbá kan lásán gẹ́gẹ́ bí àwọn onímọ̀ kan ti ṣe ṣe àlákalẹ̀ rẹ̀. Nípa wíwo iṣẹ́ pàtàkì tí à ń fi òwe ṣe ní àwùjọ àti títò òwe Yorùbá sí ààyè tó yẹ nínú ìpínsíṣọ̀rí lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá, a lérò pé ìwádìí yìí yóò rí ohun tuntutn fi kún ìmọ̀ nínú iṣẹ́ akadá.*

**Kókó-ọ̀rọ̀:** Òwe Yorùbá, Lítíréṣọ̀ alohùn, Tíọ́rì ìfìwádìí-sọ̀tumọ̀-ìṣẹ̀lẹ̀-àwùjọ

## Abstract

*The focus of this study is to examine Yorùbá proverbs as a distinct genre of Yorùbá oral literature. This study observes that many existing works on proverbs have not given sufficient attention to their standing as a specific literary genre; instead, some scholars merely regard proverbs as "ingredients" or linguistic tools for Yorùbá oral poetry. This research attempts to fill this gap by evaluating proverbs to explain their characteristics and classification within the broader context of oral literature. The methodology for this study draws from both primary and secondary sources. The primary source involved gathering Yorùbá proverbs from various aspects of Yorùbá social life, while the secondary data collection utilized relevant literature such as journals, articles, and digital resources. The collected data were analyzed using the theory of Sociological Hermeneutics. This theory was chosen specifically to examine the utility of proverbs and the roles they play in the structural framework of society. The findings of this research indicate that the role proverbs play in Yorùbá society is significant. Furthermore, an analysis of their characteristics reveals that they are much more than mere "ingredients" for other forms of oral poetry, contrary to the assertions of some scholars. By highlighting the vital functions of proverbs in society and situating them appropriately within the classification of Yorùbá oral literature, this study provides new insights for academic scholarship.*

**Keywords:** Yorùbá Proverbs, Oral Literature, Sociological Hermeneutics.

## Ìfáárà

Lẹ́gbàá ajá lẹ́sà adìẹ, kò sí ilẹ̀ táa dé tí a ò mọ ajé, bẹ́ẹ̀ni kò sí àwùjọ ènìyàn tí a dè tì a kò bá lítíréṣọ̀. Nítorí náà, a lè sọ pé lára àwùjọ kọ̀ọ̀kan ni a ti yọ lítíréṣọ̀ wọn. Ó yẹ kó lè rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé lítíréṣọ̀ àti àwùjọ ń fa ara wọn ní tẹ̀ẹ̀tẹ̀ẹ́ ni. Nídìí èyí, ó ṣòro láti gbà pé láti ibìkan ni lítíréṣọ̀ ti tàn dé àwùjọ kan nítorí pé gbogbo àwùjọ ló ní lítíréṣọ̀ tirẹ̀. Ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀ lọ́dọ̀

àwọn kan tí wọ́n gbàgbọ́ pé àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun ni atọ́kùn ọ̀làjú, àwọn náà sì ni wọ́n tanná ìmọ́lẹ̀ ìmọ̀ lítíréṣọ̀ yípo ayé. Àwíjáre wọn ni pé ohun-kóhun tí a bá ti kọ sílẹ̀ ni lítíréṣọ̀, nígbà tí ó sì jẹ́ pé òyìnbó ló mú ìmọ̀ mọ̀-ọ́n-kọ, mọ̀n-ọ́n-kà wá sí àwùjọ Adúláwọ̀. Èrò àti ìgàgbọ́ yìí hànde nínú oríkì àti àpèjúwe tí wọ́n fún lítíréṣọ̀. Àwọn Gẹ̀ẹ́sì gbà pé ohun-kóhun tí wọ́n bá ti kọ sílẹ̀ ni lítíréṣọ̀. Akiyesi tílẹ̀ fi hàn pé àwọn Gẹ̀ẹ́sì gan-an yá ọ̀rọ̀ tí a mọ̀ sí lítíréṣọ̀ láti inú èdè Látínnì wọ èdè Gẹ̀ẹ́si ni. 'Littera' ní o ń jẹ ní èdè Latinni, èyí tí ó túmọ̀ sí lẹ́ta Álífábẹ̀ẹ̀tì. Láti èdè Gẹ̀ẹ́sì ni àwọn Adúláwọ̀ ti fetí yá a wọ èdè Yorùbá. Bí a bá wo ìtumọ̀ tí àwọn Gẹ̀ẹ́sì fún lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bíi ohun-kóhun tí a bá kọ sílẹ̀, ṣe a lè pé gbogbo ohun tí a bá kọ sílẹ̀ ní ẹ̀ka ìmọ̀ mìíràn bí ẹ̀ka ìmọ̀ ìṣirò tàbí ìmọ̀ ìṣirò owó ní lítíréṣọ̀ bí? Ìdáhùn sí ìbéèrè yìí ni yóò jẹ́ kí á lè pààlà sí àpilẹ̀kọ tó jẹ́ lítíréṣọ̀ àti èyí tó jẹ́ àpilẹ̀kọ lásán.

Ẹ̀wẹ̀, àwọn onímọ̀ kan kò fi gbogbo ara gba èrò yìí wọlé nígbà tí wọ́n sọ pé a kò lè pe àkọsílẹ̀ tí kó bá ti ní iṣẹ́ ẹwà nínú ní lítíréṣọ̀. Ẹ̀mí tí àkọsílẹ̀ kọ̀ọ̀kan bá ní ni yóò fi hàn bóyá iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ ni tàbí àpilẹ̀kọ làsán. "Ẹ̀mí-iṣẹ́ yìí ni a lè tọ́kasí gẹ́gẹ́ bíi *literatunous*/*literariness*. Bí okun-kóhun tí a bá kọ sílẹ̀ bá jẹ́ lítíréṣọ̀ lọ́dọ̀ àwọn òyìnbó, ṣé àwọn Adúláwọ̀ kò ní lítíréṣọ̀ tiwọn náà ni? "Kò sáà ní jẹ́ ti baba tọmọ kó má láàlá". Ojú lítíréṣọ̀ àwọn òyìnbó nìkan ni wọ́n fi ń wo lítíréṣọ̀, bẹ́ẹ̀ kò sí àwùjọ tí kò ní lítíréṣọ̀ tirẹ̀ láàyè ọ̀tọ̀. Lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni àkójọpọ̀ ọgbọ́n, ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ àti òye Yorùbá tí a gbé kalẹ̀ pẹ̀lú ohùn ẹnu. Iṣẹ́-ọnà tí a fèdè ṣe ní ìlànà ewì, ìtàn, ìsàré, tàbí orin ni lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá jẹ. Bí a bá wo àmúyẹ tí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá máa ń ní, a ó rí i pé gbogbo àmúyẹ wọ̀nyí náà ni ó wà nínú òwe àti àlọ́ àpamọ̀ Yorùbá tí iṣẹ́ yìí dálé lórí.





Nítorí náà, a lè sọ pé òwe jẹ́ ọ̀rọ̀ ìjìnle Yorùbá ti a gé kúrú ṣùgbọ́n tí ó ní ìtumọ̀ tó kẹnú. Kòsí bí àwọn Yorùbá yóò ti sọ̀rọ̀ láìfi òwe sí i. Ìdí ni pé, gbogbo ohun tó tan mọ́ ìgbé ayé àti ìwà láàyè wọn ni ó máa ń hànde nínú òwe wọn. Kò sí ìgbà tàbí àkókò tí wọn yóò sọ̀rọ̀ tí wọn kò ní pa òwe. Ìdí nìyí ti wọn fi máa ń sọ pé "òwe lẹṣin ọ̀rọ̀…". Bákan náà ni àlọ́ àpamọ̀ sì jẹ́ ọ̀rọ̀ àdììtú tí ó ń fún àwọn ènìyàn ní òye àti ọgbọ́n. Àwọn èyà yìí jẹ́ ìpìlẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn, tí wọ́n sì ṣe pàtàkì nínú ẹ̀kọ́ ìgbàlọ́de, àti ìdàgbàsókè àwùjọ Yorùbá.

Ìwádìí yìí yóò ṣe àfihàn bí òwe gẹ́gẹ́ bí ìpínṣíṣòrí èyà lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Bó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn onímọ̀ lítíréṣọ̀ ti ṣe ìwádìí lórí òwe àti àlọ́ àpamọ̀ lọ́pọ̀lọpọ̀, ṣíbẹ̀ àwọn ìwádìí tí ó wà nílẹ̀ kò tíì walẹ̀ kan gbòngbòn lórí ìpínsísọ̀rí lítíréṣọ̀ tí a lè kàwọ́n mọ́. Nítorí náà, a lè sọ pé iṣẹ́ ìwádìí kò tíì rinlẹ̀ tó lórí àgbéyẹ̀wò òwe àti àlọ́ àpamọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, tí ó sì fi ìmọ̀ òfin ìṣèlú àwùjọ lítíréṣọ̀ hàn bí wọ́n ṣe ń ṣàfihàn àwùjọ Yorùbá. Ìwádìí yìí yóò fi kún ìmọ̀ nípa bí àwọn èyà lítíréṣọ̀ yìí ti ṣe ṣe pàtàkì nínú ìgbé-ayé, àti àṣà àwùjọ Yorùbá. Ìwádìí yìí yóò lo ìlànà àtúnyẹ̀wò àfihàn (qualitative descriptive analysis), tí yóò gbéra lórí àwọn òwe tí a gbà láti ọ̀dọ̀ àwọn àgbàlagbà ní àwùjọ Yorùbá àti àwọn ìwé lítíréṣọ̀ Yorùbá. A ó ṣe àfihàn àwọn òwe ní ìbámu pẹ̀lú ìlò wọn nínu ìhun àwùjọ̀, tí a ó sì lo tíọ́rì ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀-ìṣẹ̀lẹ̀-àwùjọ ṣàlàyé ìtumọ̀ rẹ̀.

## Tíọ́rì Ìsàmúlọ̀

Tirì ìsàmúlò fún ìwádìí yìí gbéra lórí ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀-ìṣẹ̀lẹ̀-àwùjọ (Sociological Hermeneutics). Ìlò tíọ́rì fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ ṣe pàtàkì gan-an nítorí pé ó ń fúnni ní òye tí ó jinlẹ̀ lórí bí lítíréṣọ̀ ṣe ń ṣàfihàn àwùjọ, ìgbé ayé, àti àṣà ènìyàn. Tíọ́rì yìí

ko ṣàlàyé ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ nìkan ṣùgbọ́n ó tún ṣe àfihàn bí àwọn ìṣòro àwùjọ ṣe ń hàn nínú iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ṣíṣe àmúlò tíọ́rì fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ kì í ṣe kàn-án-pá, ṣíbẹ̀, ó jẹ́ ìlànà tí ó máa ń mú àyẹ̀wò iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ rọrùn tí yóò jẹ́ kí iṣẹ́ náà ó gbóúnjẹ-fẹ́gbẹ́-gbàwo-bọ̀ láwùjọ akadá. Nítorí náà, ìwádìí yìí ṣe àmúlò tíọ́rì ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀-ìṣẹ̀lẹ̀-àwùjọ (Sociological Hermeneutics) fún ìwádìí yìí, èyí tí ó ń fi hàn pé lítíréṣọ̀ jẹ́ àfihàn àwùjọ àti bí ó ṣe ń ṣe àwùjọ Yorùbá lójoojúmọ́.

## Tíọ́rì Ìfiwádìí-Sọ̀tumọ̀-ìṣẹ̀lẹ̀-àwùjọ (Sociological Hermeneutics)

Tíọ́rì ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀-ìṣẹ̀lẹ̀-àwùjọ jẹ́ àkànpọ̀ tíọ́rì ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀ (Hermeneutics) àti tíọ́rì ìfojú ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo lítíréṣọ̀ (Sociology of Literature). Àkíyèsí fi hàn pé àwọn onímọ̀ tíọ́rì a máa ṣe àkànpọ̀ tíọ́rì méjì láti sọ ọ́ di ọ̀kan tí irúfẹ́ tíọ́rì náà yóò si máa ṣiṣẹ́ méjì papọ̀. Irú rẹ̀ ni tíọ́rì yìí. Ìwádìí jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé láti inú tíọ́rì ìfojú-inú-wo-ẹ̀mi-ara-nǹkan (phenomenology) ni tíọ́rì ìfiwádìí-sọ-ìtumọ̀ ti jẹ jáde. Tíọ́rì ìfojú-inú-wo-ẹ̀mí-ara-nǹkan gbà pé gbogbo ohun tí ó wà láyé kò dá wà láìní nǹkan ṣe pẹ̀lú ara àwọn ènìyàn. Edmond Husserl (1964) tí ó dá tíọ́rì yìí sílẹ̀ gbà pé bí a bá fojú inú wo nǹkan ló lè jẹ́ kí àjọṣepọ̀ wà láàrin ohun tí à ń fojú inú wò náà àti èrò ọkàn ẹni. Ó tẹ̀síwájú pé ojú tí a fi n wo iṣẹ́ àti èrò inú wa gan-an ló lè fún iṣẹ́ kan ní ìtumọ̀ kì í ṣe èdè rárá. Ipò tí Husserl fi èdè sí nínú fífún iṣẹ́ ní ìtumọ̀ ló mú kí Heidegger (1962) tako èrò yìí nítorí pé èdè ti wà kí ó tó di pé àwa ẹ̀dá wà. Láìsì sí èdè kò lè sí ohun tí ó ń jẹ́ ìtumọ̀. Heidegger tilẹ̀ tún sọ síwájú pé kò pọn dandan kí lámèétọ́ máa wá ìtumọ fún iṣẹ́ kan. Ó ní fúnra iṣẹ́ tí à ń wò ni yóò sọ ìtumọ̀ ara rẹ̀ bí a bá fi ara wa sílẹ̀ fún iṣẹ́ náà bí o ṣe yẹ kí lámèétọ́ ó ṣe é.





Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ìwé ẹ̀sìn nìkan ni wọ́n ń fi tíọ́rì ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀ túpalẹ̀ tẹ́lẹ̀, ìtẹ̀síwájú ìmọ̀ jẹ kí á mọ̀ wí pé onírúurú lítíréṣọ̀ ní à ń lò ó fún báyìí. Tíọ́rì ìfiwádìí-sọ-ìtumọ̀ gbà pé ìtumọ̀ iṣẹ́ ṣe pàtàkì púpọ̀. Ìdí nìyí tí Gadamer àti Iser (1980) fi fi ògún rẹ̀ gbárí pé ìtumọ̀ tí òǹkòwé yóò bá fún iṣẹ́ kan kò lè kọjá àwùjọ rẹ̀ pàápàá nípa ìrírí, èdè àti àṣà. Nítorí náà, ìtumọ̀ tí a ó fún iṣẹ́ lítírésọ̀ fẹ̀ púpọ̀ ju ọ̀wọ́ ohun tí ó wà lọ́kàn òǹkòwé lọ nígbà tí irú òǹkòwé bẹ́ẹ̀ ń kọ ìwé rẹ̀. Tíọ́rì ìfiwádìí-sọ-ìtumọ̀ kò gbà pé ìtumọ̀ lítíréṣọ̀ kan wà lódidi. Kélekèle ní ó wà, òǹkàwé sì ní láti to àwọn ìtumọ̀ inú lítíréṣọ̀ jọ kí kókó-ọ̀rọ̀ inú lítíréṣọ̀ náà ó lè hàn sí wa. Gbogbo àtòpọ̀ àti ìtumọ̀ tí òǹkòwé kọ̀ọ̀kan bá ṣe kò lè má yàtọ̀ ṣùgbọ́n ìyàtọ yìí kò lè fi bẹ́ẹ̀ pọ̀ rárá. Ìdí nìyí tí tíọ́rì yìí fi dábàá pé kí òǹkòwé bèèrè ìbéèrè tí ó mọ́yán-lórí lórí lítíréṣọ̀ tó fẹ́ túmọ̀ náà. O ní bí a bá lè ṣe èyí, a jẹ́ pé a lè sọ ohun tí ọ́ wà ní ọkàn òǹkòwé nígbà tí ó ń kọ ìwé rẹ̀.

Bí a bá tún wo tíọ́rì yìí dáadáa, a lè pè é ni tíọ́rì ìfiwádìie sọ̀tumọ̀ lọ́na tó gbòòrò. Ọ̀ọ̀dúnrún kẹrìǹdínlógún ni wọ́n dá tíọ́rì yìí sílẹ̀ ní ilẹ̀ Germany ní dún 1838 pẹ̀lú Friedrich Schleiermacher àti Wilhelm Dilthey. Schleiermacher ṣe àgbékalẹ̀ tíọ́rì ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀-ìṣẹ́lẹ́-àwùjọ gẹ́gẹ́ bi àtúnṣe hermeneutics èyí tí ó dá lórí òǹkọ̀wé (author) àti àṣà tó yí i ká, Dilthey sì kà àkíyèsí náà sí i ní ọ̀rọ̀ tí ó níí ṣe pẹ̀lú sáyẹ́nsì awùjọ látàrí pé kí a lóye ìrírí ẹ̀dá ènìyàn, kì í ṣe ìwádìí àfihàn àjọṣe tó kàn. Àríwísí Hans-Georg Gadamer yàtọ̀ sí i nípa àfihàn àkọ́sílẹ̀ ìlànà tíọ́rì ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀ àti ìmọ̀ àwùjọ tó fihàn bí ìtumọ̀ ohun tó rọ̀ mọ́ ìgbé-ayé ẹ̀dá ní àwùjọ ti ṣe rí.

Àwọn ìlànà pàtàkì nínú tíọ́rì ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀-ìṣẹ́lẹ́-àwùjọ (Sociological Hermeneutics) ni pé ìtúpalẹ̀ òye jẹ́ ọ̀rọ̀ àjọṣepọ̀ àti àyíka, ó sì jẹ́ pé kò ṣeé yẹ̀ kúrò níbi àkókò àti àṣà tí

Ondo Journal of Arts, Faculty of Arts, Adeyemi Federal University of Education, Ondo. Vol. 2. No. 1&2, 2026 | Òwe Yorùbá Gẹ́gẹ́ bi Ìpínṣísọ̀rí Ẹ̀yà Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá

ọrọ̀ náà ti wá. Èyí jẹ́ kí tíọ́rì ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀-ìṣẹ́lẹ́-àwùjọ (Sociological Hermeneutics) jẹ́ pátákì fún ohun èlò àtúnyẹ̀wò ìtúpàlẹ̀ ìhun àfiwé òwè àti àlọ́ àpamọ̀ Yorùbá, níbi tí ọ̀rọ̀ àti ìtumọ̀ ti dá lórí àyíká, àwọn àmì àṣà, àti ìbáṣepọ̀. Tíọ́rì ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀-ìṣẹ́lẹ́-àwùjọ nínú ìtúpalẹ̀ ìhun àfiwé òwè àti àlọ́ àpamọ̀ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ìpínṣísọ̀rí Ẹ̀yà Lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá jẹ́ kí a mọ̀ nípa àyẹ̀wò tó jinlẹ̀ nípa bí ìtumọ̀ ṣe ń yí padà ní àwùjọ àti ìtàn, tí ó ń fojú han nínú àṣà.

Ìdí tí a fi yan tíọ́rì yìí lááyọ̀ ni pé, tíọ́rì yìí wúlọ̀ fún àyẹ̀wọ̀ iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ láti tọpinpin ìtumọ̀ tí òwe pẹ̀lú àlọ̀ àpamọ̀ ní awujo. Àkíyèsí fi hàn pé àwùjọ́ kọ̀ọ̀kan ló ní àwọn òwe tí ó gbajúmọ̀ níbẹ̀ àti àlọ́ àpamọ̀ wọn tó hàndè. Ẹ̀wẹ̀, tíọ́rì yìí tún fún wa ní àǹfààní láti fún òwe tàbí àlọ́ àpamọ̀ tí a ti kọ láti ọjọ́ tí ó ti pẹ́ ní ìtúmọ̀ ijinlẹ̀ tí ó rọ̀ mọ́ àwùjọ tí a wà lónìí. Tíọ́rì ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀-ìṣẹ́lẹ́-àwùjọ yóò jẹ́ kí a lè fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé òwe jẹ ẹ̀yà ewì alohùn Yorùbá. Àlàyé tí a fẹ́ ṣe nípa òwe Yorùbá pẹ̀lú àlàyé pé ó jẹ́ ẹ̀yà ohùn ẹnu nínú ìmọ̀ Fókìilọ̀ tí ó gba àròjinlẹ̀ pẹ̀lú àgbékalẹ̀ èdè tó nípọ̀n tí ó sì nílò àlàyé kíkún kí ìtumọ̀ rẹ̀ tó lè yéni yékéyéké.

Nípa lílo tíọ́rì Ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀-ìṣẹ̀lẹ̀-àwùjọ (Sociological Hermeneutics) yìí kò wo òwe gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ lásán, ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́ bí 'ohun èlò' (social tool) tí Yorùbá ń lò láti tún ìwà ọmọlúàbí kọ́, láti yanjú aáyan, àti láti tọ́jú àwọn ìtàn àtẹnudẹ́nu tí ó jẹ́ kókó fún ìdúró-ṣinṣin àwùjọ.

**Aáyan Àwọn Ọ̀mọ̀ràn Ìṣaájú lórí Òwe Yorùbá**

Àwọn onímọ̀ bíi Bamgbose (1968) àti Olatunji (1984) ti sìṣẹ́ takuntakun lórí ìhun àti ìlò òwe Yorùbá, ṣùgbọ́n ọ̀nà tí iṣẹ́ yìí gbà yàtọ̀ ni pé, ó tako èrò pé òwe jẹ́ 'èròjà' lásán fún ẹ̀yà ewì



mìíràn. Iṣẹ́ yìí fẹ́ gbé òwe kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn láyè ọ̀tọ̀ láì jẹ́ pé ìwàláàyè rẹ̀ gbáralé tàbi rọ̀gbọ̀kú ẹ̀yà mìíràn. Ọ̀kan-ò-jọ̀kan àlàyé ni àwọn onímọ̀ ti ṣe lórí àkójọpọ̀, orísun, ìtumọ̀, ìwúlò, àpèjúwe, àbùdá àti ìhun òwe, ìtúpalẹ̀ ìlò-èdè àti ọ̀nà-èdè inú òwe Yorùbá ṣùgbọ́n wọ́n kò kọbiara sí ipò tí òwe Yorùbá wà nínú ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, èyí sì ni àlàfo tí a fẹ́ dí nínú ìwádìí yìí.

Lára àwọn onímọ̀ tí wọ́n ti ṣiṣẹ́ lórí òwe Yorùbá, ni a ti rí Ajíbọ̀lá (1974), Fásànyà (1962), Délànọ̀ (1966), Bámgbọ́ṣé (1968), Badà (1973), Akínlàdé (1982), Olátúnjí (1984), Akínmádé (2005), Atóyèbí (2006), Hornby (2006), Fásíkà (2006), Sheba (2006), Akíntúndé (2008), Akínyẹmí (2008), Babade (2008), Oyèdèjì (2010), Oláoyè (2012), Atóyèbí (2014), Fátùrótì (2014), Akinọlá (2016), Ehineni (2016), Àlàbí (2018) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Bí a ti ri àwọn tí ó kọ ìwé lórí òwe bẹ́ẹ̀ náà ni a rí àwọn tí wọ́n kọ átíkù lórí òwe nínú jọ́nà. Àwọn mìíràn bí Ajíbọ̀lá (1947), Délànọ̀ (1966) àti Babade (2008) ṣe àkọsílẹ̀ òwe nínú ìwé wọn pẹ̀lú ìtumọ̀ rẹ̀ ní èdè Gẹ̀ẹ́sì. Beier àti Gbàdàmọ́sí (1959:60-64) ṣe àgbéyẹ̀wò èrò tí ó ń fi ojú àmúwayé Yorùbá hàn nínú òwe. Wọ́n tún ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé nípa ọ̀nà tí òwe ń gbà kọ́nilẹ́kọ̀ọ́ ìwà ọmọlúàbí, kìlọ̀ ìwà àti ọ̀nà tí òwe ń gbà fi ìmọ̀lára hàn. Ṣóbándé (1967) ṣe ìpínsí òwe Yorùbá ní tirẹ̀ sí ọ̀nà mọ́kànlá. Bí àpẹẹrẹ, àwọn òwe tí ó ṣàlàyé ara wọn, òwe tí ó ń yán ọ̀rọ̀ fẹ́ẹ́rẹ́, òwe onítumọ̀, òwe àtinúdá, òwe tí ó jẹyọ nípase ẹ̀sìn Mùsùlùmí, ẹ̀sìn Ọmọlẹ́yìn-Jésù àti àwọn orin arọ̀mọ́gbà àti àwọn òwe tí ó tọ́ka sí àwọn ẹ̀yà ara. Ọdúnjọ (1969) ṣàgbéyẹ̀wò orísun òwe láti ara àwọn àkíyèsí ìṣẹ̀lẹ̀ àyíká àti ìbáṣepọ̀ láàrin ọmọ ènìyàn. Bámgbóṣé (1968) ṣàpèjúwe ìhun òwe Yorùbá, nípa wíwo bátànì gbólóhùn inú wọn - gbólóhùn

abódé, gbólóhùn oníbọ̀, aìbádọ́gba, ẹyọ ọ̀rọ̀, wúnrẹ̀n gírámà àkíyèsí ẹ̀ka-èdè àti ìfọ̀rọ̀dárà inú òwe Yorùbá. Ọlátúnjí (1984) ṣàlàyé nípa ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ òwe, orísun òwe, àkóónú òwe, ìfojú-inú-yàwòrán nínú òwe àti àbùdá òwe. Bada (1973) náà ti ṣàlàyé púpọ̀ nípa òwe Yorùbá àti ìṣẹ̀dá wọn. Ó jẹ́ kí á mọ̀ wí pé òwe máa ń mú ọ̀rọ̀ túbọ̀ dùn sí i, kì í sì jẹ́ kí á gbàgbé ọ̀rọ̀ bọ̀rọ̀ àti pé púpọ̀ nínú òwe Yorùbá ló ti inú Odù Ifá, àlọ́, ìrírí àyíká àti ọ̀rọ̀ wa. Ìdí tí Odù Ifá fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé púpọ̀ Odù Ifá ni ó jẹ́ ìtàn atọwọ́dọ́wọ́. Èyí fi hàn pé nínú ìrírí àti ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ Yorùbá ni òwe ti jẹ yọ. Lára ẹ̀rí tí a fi mọ̀ pé ọ̀pọ̀ òwe Yorùbá ló jẹ́ pé inú odù Ifá ní ó ti jẹ yọ ni ohun tí a gbọ́ lẹ́nu abẹ́nà-ìmọ̀ wa Babaláwo Awolọ́wọ̀ Agbójúléfá, Àràbà Awo tí ìlu Ìka-Ọ̀ràngún ní ìjọba ìbílẹ̀ Èjìgbò ní ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun, nígbà tí ó fi ẹsẹ Ifá ìsàlẹ̀ yìí gbe ọ̀rọ̀ rẹ̀ lẹ́ṣẹ̀ pé, bí a bá pa òwe kan a kàn ní láti fi a dífá fún sí i ni. Bí àpẹẹrẹ:

“Ọ̀rẹ́ kítí kítí
Ìyèkan kàtà-kàtà
Ọjọ́ tí ọ̀rẹ́ kítí-kítí bá kú
Ìyèkan kàtà-kàtà níí kù
A díá fún Àbe tíí ṣe olóore ìgbà ìwáṣẹ̀”
(Olóyè Awólọ́wọ̀ Awógbilé)

Àpẹẹrẹ mìíràn:

“Ohun tí ẹnu rí ni ẹnu ń jẹ
A díá fún èkòlò tí yóò jẹ ilẹ̀ yó…”
(Olóyè Awólọ́wọ̀ Awógbilé)

Bákan náà, a tún rí irúfẹ́ àpẹẹrẹ yìí nínú ẹsẹ-Ifá ìsàlẹ̀ yìí:

“ọwọ́ ọmọdé kò tó pẹpẹ
Tàgbàlagbà kò wọ akerèngbè
Iṣẹ́ tí èwe bá bẹ àgbà kó má kọ̀ mọ́
Gbogbo wa ní a ni iṣẹ́ jẹ́ fún ara wa



Ondo Journal of Arts, Faculty of Arts, Adeyemi Federal University of Education, Ondo. Vol. 2. No. 1&2, 2026 | Òwe Yorùbá Gẹ́gẹ́ bi Ìpínṣíṣọ̀rí Ẹ̀yà Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá

A díá fún Ọ̀rúnmìlà tí Akápò rẹ̀ yóò pè é lẹ́jọ́”
(Abímbọ́lá, 2006)

Àwọn onímọ̀ ti ṣe àfihàn bí òwe ṣe ti ṣe pàtàkì nínú ìmọ̀ ìbílẹ̀, èdè, àṣà, àti ìdàgbàsókè àwùjọ. Òwe Yorùbá kì í ṣe eré lásán, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ohun èlò tí ó ń fúnni ní òye ìjinlẹ̀ lórí ìgbé-ayé, ìkọ́ni, àti ìṣèlú. Adégbìtẹ́ (2025), jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé òwe ń ṣe àfikún sí òye Yorùbá. Ìwádìí yìí fi hàn pé òwe jẹ́ ìpìlẹ̀ fún ìmọ̀ ilẹ̀ Adúláwọ̀ tí ó yẹ fún ìdàgbàsókè èdè àti àṣà. Lọ́nà kan náà, Olúwadọ̀rọ̀ aayr. (2025) ṣe ìtúpalẹ̀ bí òwe Yorùbá ṣe ń yí padà nítorí ìdàgbàsókè ìmọ̀-ẹ̀rọ, ìṣèlú, àti àwọn ìṣòro bíi ìpániláyà àti àjàkálẹ̀-àrùn, nípa fífúnni ní àwọn òwe bíi "Ọwọ́ ọmọdé kò tó pẹpẹ, tàgbàlagbà ò wọ kèngbè" tí ìmọ̀-ẹ̀rọ ti yí ìtumọ̀ rẹ̀ padà. Ìwádìí yìí fi hàn pé òwe kò dúró ní ìgbà àtijọ́, ṣùgbọ́n ó ń yí padà pẹ̀lú àkókò. Salahu-Deen àti Ọláwálé (2025) ṣe àfihàn àwọn òfin bíi ìbọ̀wọ̀ fún àgbà àti ìfaradà nínú àwọn òwe. Babalọlá àti Àtàndá (2024) ṣe ìtúpalẹ̀ bí òwe Yorùbá ṣe ń fi àwọn òfin ìṣèlú hàn, bíi ìgbéṣe, ìfọ̀kanbalẹ̀, àti ìṣọ̀kan, tí ó jẹ́ ìpìlẹ̀ fún ìdàgbàsókè àjọ àti ìṣèlú ìgbàlódé, nípa fífúnni ní òye àwùjọ adúláwọ̀. Àwọn ìwádìí yìí fi hàn pé òwe Yorùbá tún ṣe pàtàkì nínú ìṣèlú àwùjọ, ìkọ́ni, àti ìdàgbàsókè èdè láyé òde òni, tí yóò sì ṣe àmúṣe fún ìwádìí mìíràn. Aáyan àwọn ọ̀mọ̀ràn ìṣaájú tí a yẹ̀wò nípa òwe Yorùbá yìí yóò ràn wá lọ́wọ́ láti fi ṣe àtẹ̀gùn nínú iṣẹ́ wà lórí àgbéyẹ̀wò òwè àti àlọ́ àpamọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá.

## Òwe Yorùbá

Pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àlàyé tí àwọn onímọ̀ ìṣaájú ti ṣe lórí òwe Yorùbá, àkíyèsí fi hàn pé ọ̀kan lára èso àwùjọ ni òwe Yorùbá jẹ́. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé gbogbo ohun tí ó jẹmọ́ ìgbé-ayé ẹ̀dá pátá ni a ti máa ń bá òwe Yorùbá pàdé. Èyí ni ó jẹ́ kí á ní onírúuru ẹ̀yà tàbí ẹ̀ka tí òwe Yorùbá pín sí. Lára rẹ̀ ni a ti ní òwe tí ó

jẹmọ́ ìṣẹ̀lẹ̀ bíi, ọdún, ìgbà, àkókò, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lo. A tún ri òwe tí ó jẹmọ́ akọ àti abo, bẹ́ẹ̀ sì ni a rí èyí tó jẹmọ́ ojú ara takọ tabo. Òwe tí ó ń tọ́ka sí ẹ̀yà ara náà wà. Bákan náà ni a ni òwe tí ó n júwe ìwà ẹ̀dá ní àwùjọ. Ìtàndòwe wà, òwe ìgbàlódé, òwe àtijọ́, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nínú iṣẹ́ yìí a ó ṣe àgbéyẹ̀wò ìwọ̀nbà tí agbára bá ká láti fi pàjùba ọ̀gangan ibi tí a fẹ roko tọ̀.

## Ìtàn Olówe / Ìtàndòwe

Ìtàn olówe / ìtàndòwe yìí ló jẹ́ ìtàn tí ó máa ń jẹ jáde lóòrèkóòrè nínú òwe àti àṣàyàn ọ̀rọ̀ nínú èdè Yorùbá. Ó máa ń fi ara jọ ìyán-ọ̀rọ̀-fẹ́ẹ́rẹ́, ìdí ní pé àwọn afèdèsọnà máa ń ṣe àmúlò rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí fọ́nrán àkòrí fún irú òwe bẹ́ẹ̀. Ẹ wo àpẹẹrẹ díẹ̀;

### Èébú àlọ ni ti ahun àbọ̀ ni ti àna rẹ̀

Òwe yìí jẹ yọ láti inú àlọ́ onítàn kan níbi tí alábahun (ìjàpá) ti ṣe asemáṣe sí ọ̀dọ̀ àna rẹ̀ (ìgbín) tí àna rẹ̀ sì dá sẹ̀ríà fún un tí ó ní kí wọn ó ṣe ìjàpá ní alóre sí gbàgede kí èrò àlọ èrò àbọ̀ ó lè mọ irúfẹ́ ìwà àìlójùtí tí ó ṣe sí sàkání àna rẹ̀. nígbà tí wọ́n ṣe èyí tán gbogbo àwọn ènìyàn tí wọ́n ń lọ oko láàárọ̀ tí wọ́n bá ti kọjá tí wọ́n tí rí ìjàpá í ṣe ni wọ́n ń bú u pé aláìdara ni ṣùgbọ́n nígbà tí ọjọ́ rọ̀ tí wọ́n ń bọ̀ wá sílé tí wọ́n tún bá ìjàpá níbẹ, wọ́n pa ohùn pà tí wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ sí ní bú àna rẹ̀ pé 'háwù bí kò bá wá ṣe àna wọn ń kọ́ ṣe wọn yóò pa á ni?" láti ìgbà yìí ni ìtàn yìí ti di òwe di òní. Àwọn Yorùbá máa ń lo òwe yìí ní òòrèkóòrè tí wọ́n bá ń sìpẹ̀ fún ẹnìkan tí ẹni tí wọ́n ń bẹ̀ sì fẹ́ fi ààkẹ̀ kọ́rí wọ́n máa ń fi òwe onítàn yìí sín in ní gbẹ́rẹ́ ìpàkọ́

### Dàda kò le jà ṣùgbọ́n ó ní àbúrò tó gbójú

Àjàkà aláàfin Ọ̀yọ́ kejì ní wọn ń pé ni Dàda òun sì ni ẹ̀gbọ́n Tella Òkò tí a mọ̀ sí Ṣàngó aláàfin ìkẹta. Ìtàn jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé Dàda jẹ́ ènìyàn pẹ̀lẹ́, oníwà tútù bí àdàbà ni, kìí ṣe èèyàn tí ó ní aápon, àìní aápọn rẹ̀ yìí náà ní ó jẹ́ kí Olówu ìgbà náà ó tẹ̀ ẹ́ mọ́ ẹrẹ̀ tí ó sì ta àbàtà sí aṣọ àláárì rẹ̀. Ṣùgbọ́n Ṣàngó àbúrò rẹ̀ eni tí ó gbójú gbójà tí ó sì nípọn láyà bí ìrán dìde, tí ó sì kọ ìyà fún ẹ̀gbọ́n rẹ. láti ìgbà yìí ni ó ti di òwe fún àwon ará Ọ̀yọ́ títí dé gbogbo ilẹ̀ kóótu-o-jíire tí wọ́n fí máa n pa òwe pé "Dàdà ò le jà o, ṣùgbọ́n ó ní àbúrò tó gbójú". Àwọn Yorùbá máa ń lo òwe yìí nínú èyíikèyí ẹ̀yà ìmọ̀ ìgbé-ayé-ẹ̀dá láwùjọ pàápàá àwọn tí ó jẹmọ́ ohùn ẹnu nígbà tí wọ́n bá fẹ́ fi ọ̀rọ̀ rọ̀ọgun sí ẹni tí àìlágbárá bá se bí ẹni fẹ́ dami tútù sí lọ́kàn láti máa kááàrẹ̀ ọkàn nígbà tí wọ́n bá sẹ àkíyèsí pé ohun tí kó le ṣe àwọn tí wọ́n wà ní sàkání rẹ̀ le ṣe jù bẹ́ẹ̀ lọ.

## Òwe Nínú Ọfọ̀/ Òwe Ajẹmọ́fọ̀

Ọ̀kan lára ewì àwíṣẹ ni ọfọ̀ jẹ́. Ó sì ní àbùdá bí-í-tí-rí bẹ́ẹ̀ ni, bí-í-tí-rí bẹ́ẹ̀ kọ́ àti bí-tí-rí ti kání. Ọfọ̀ tún ní àbùdá apè láti pé àwọn ẹ̀mí àìrí wá si tòsí lọ́nà àtilè mú ìfẹ́ inú apòfò ṣe. Kì í ṣe àlàyé nípa ọfọ̀ ní ó jẹwa lógún níhìn ṣùgbọ́n kí á máa ṣe alàìsọ̀rọ̀ díẹ̀ bí àlékún ni… Ohun tí ó ṣe pàtàkì síwa ni àwọn òwe tí ó máa ń hànde gẹ́gẹ́ bi ọfọ̀ nínú ìmọ ìgbé-ayé ẹ̀dá láwujọ àjẹmọ́ ohùn ẹnu verbal folk) ló jẹwá lógún. Àwọn òwe Yorùbá kan wà tí ó jẹ wí pé wọn máa ń ṣe àmúlò ọfọ̀ nínú àgbékalẹ̀ wọn. Àwọn òwe wọ̀nyí jẹ́ èyí tí wọ́n ní ète ìdánilójú tàbí ìdánwò kan, tí wọ́n sì fara jọ ọfọ̀ nínú bí wọ́n ṣe ń lo àwọn ohun àmúṣẹ láti fi ìdí ọ̀rọ̀ múlẹ̀ lójú ẹni tó ń gbọ́. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ díẹ̀:

**Ojú kì í ri arẹwà kí ó má kí i**

Òwe yìí wà nínú ọ̀fọ̀ **Bí-í-tí-rí bẹ́ẹ̀ ni**. Ó ń lo ìṣe àdánidá ojú láti fi sọ pé ohun tí ó dára tàbí tí ó rẹwà kò gbọ́dọ̀ lọ láìjẹ́ ti òun, tàbí pé ohun tí ó dára ni gbogbo ènìyàn ń wò tàbí ń fẹ́. Gẹ́gẹ́ bí ọ̀fọ̀, ó ń fún ọ̀rọ̀ ní agbára ìdánilójú pé **kò sí àyè fún àìṣẹlẹ̀** ohun tó dára. Àwọn Yorùbá a máa lo òwe yìí nígbà tí wọ́n bá fẹ́ ṣe àpọ́nlé nǹkan tàbí sọ pé ènìyàn kò lè ṣe láìṣe nǹkankan.

**Òwú kì í là kínú ó bí olóko**

Òwe yìí náà tún wà nínú ọ̀fọ̀ **Bí-í-tí-rí bẹ́ẹ̀ ni**. Ó ń lo òtítọ́ nípa bí òwú ti ṣe ń là nínú ọkọ, tí ó sì ń yọ síta bí èso. Ète rẹ̀ ni láti fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé bí òwú ṣe ń yọ jáde lára igi, bẹ́ẹ̀ ni nǹkan tí ó dára tàbí èrè yóò ṣe yọ jáde lára iṣẹ́ ẹni, yálà èrè nípa ọ̀rọ̀ ẹnu tàbí èrè nínú ohun tí ẹnìkan ń ṣe. Ó fẹ́ fi agbára ìdánilójú gidi ti ọ̀fọ̀ múlẹ̀ pé **ètè tí ó wà nínú ọ̀rọ̀/àṣẹ náà gbọdọ̀ yọ jáde**. Bí àwọn Yorùbá bá pa òwe yìí wọ́n fẹ́ kí ó di mímọ̀ pé bí ọ̀rọ̀ ẹni bá ń dayọ̀/ dára, inú kò gbọdọ̀ bí àwọn ènìyàn tí wọ́n wà ní àyíká ẹni.

**Eégún kì í ṣíwọ́ títẹ̀kí òǹṣòwò títẹ̀kí olóko**

Ó ń tọ́ka sí ìwà àdámọ́ eégún tí ó jẹ pé kò sí ibi tí kò le wọ̀. Àwọn Yorùbá máa ń lo òwe yìí láti fi agbára eégún hàn. Ó sì jẹ́ fọ́nrán ọ̀fọ̀ bí-tí-rí-bẹ́ẹ̀ ni tí ó jẹ́ àbùdá ọ̀fọ̀ tí ó ṣe àfihàn asẹ̀málù, pé bí wọ́n ti ṣe ń fi ọ̀wọ̀ wọ eégún ni kí wọn ó fi ọ̀wọ̀ wọ ènìyàn. Àwọn òwe wọ̀nyí ṣe pàtàkì nítorí wọ́n ń gbé ìmọ̀ ìgbàgbọ́ Yorùbá wọ inú ọ̀rọ̀ ìjẹmọ́-ohùn ẹnu. Wọ́n ní agbára ọ̀fọ̀ tó ń sọ pé. Ìlò àwọn òwe ajẹmọ́fọ̀ yìí kò jẹ́ ọ̀rọ̀ lásán, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ìlò àṣẹ lórí àyíká tàbí àṣẹ lórí ipò kan.





**Òwe Nínú Ẹṣẹ-Ifá/ Òwe Ajẹmẹ́ṣẹ-Ifá**

Ẹṣẹ-Ifá náà jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú ewì alohùn Yorùbá. Ẹṣẹ-Ifá máa ń ní àbùdá, “a díá fún” àti “àyájọ́” nínú. Ọ̀pọ̀ òwe Yorùbá ló sì jẹyọ nínú ẹṣẹ-Ifá. A tilẹ̀ le sọ pé ó fẹ́rẹ̀ má si ẹ̀yà ìmọ̀ ìgbé-ayé-ẹ̀dá láwùjọ ajẹ́mọ́ ohùn ẹnu tí a ò ní rí ìbátan rẹ̀ pẹ̀lú ẹṣẹ-Ifá. Èyí fi hàn pé ẹṣẹ-Ifá máa ń ṣe àmúlò òwe púpọ̀. Ẹ jẹ́ á wo díẹ̀ nínú àwọn àpẹẹrẹ òwe tí a lè rí sàjọ tí wọ́n ṣe àmúlò ẹṣẹ-Ifá:

**Ọ̀rẹ́ ò gbẹlẹ̀ta, èjì lọ̀rẹ́ gbà**

Òwe yìí wá látinú ìtàn kan nínú odù Ifá tó máa ń kọ́ wa nípa ìkìlọ̀ nípa wíwá ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀rẹ́. Ó ń ṣàlàyé pé nígbà tí ìjà bá fẹ́ bẹ́ sílẹ̀ láàrín àwọn ọ̀rẹ́ púpọ̀, ọ̀kan péré ló máa jẹ́ olóòótọ́ tó máa gbè ọ́ lẹ́yìn (ìyẹn ni pé ọ̀rẹ́ méjì péré ló máa wà nínú ìyẹn: ìwọ àti olóòótọ́ ọ̀rẹ́ rẹ), tàbí pé méjì péré ló lè jẹ́ òtítọ́ nínú gbogbo wọn. Ó ń rọ àwọn ènìyàn láti yan ọ̀rẹ́ pẹ̀lú ọgbọ́n tàbí kí wọ́n wà ní ìṣọra gidigidi (ìmọ̀ àyànjú ọ̀rẹ́/ètò ìgbésí ayé). Èyí tí ó túmọ̀ sí pé ọ̀rẹ́ kíkójọ kò dára nítorí pé ewu wà níbẹ̀. Ìdí niyí tí Yorùbá fi máa ń sọ pé “àyànjù ọ̀rẹ́ ní í múni yan èké” àtipé ẹni tí ọ̀rẹ́ kò bá tí ì fi ìwà hàn ni yóò pé irú ọ̀rẹ́ òun ò sí láti ìgbà tí mo ti mọ ìwà ọ̀rẹ́ mi, ni mo ti mọ ìwà arámi, orin mi kọ́ orin baba mi kan ni.

**Ọpẹ́lọpẹ́ èjìká tí kò jẹ́ kí èwù ó bọ́...**

Ẹsẹ́ Ifá tí ó wà lẹ́yìn òwe yìí máa ń tẹnu mọ́ ìwà ìmoore àti wíwá ìdúróṣinṣin. Èjìká ni ó ń gbé aṣọ dúró, bí Olóore/Ọlọ́run ṣe ń jẹ́ kí ìgbésí ayé wa dára. Òwe yìí jẹ́ ìwúrí láti mọyì àwọn ohun tí ó ń jẹ́ kí nǹkan rí bẹ́ẹ̀ fún wa (gẹ́gẹ́ bí Orí ẹni tàbí baba rere tó bí ni)

Ondo Journal of Arts, Faculty of Arts, Adeyemi Federal University of Education, Ondo. Vol. 2. No. 1&2, 2026 | Òwe Yorùbá Gẹ́gẹ́ bi Ìpínṣíṣọ̀rí Ẹ̀yà Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá

**Kò sí òrìṣà tíí dáni gbè bí kò ṣe orí ẹni**

Èyí jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn òwe tó gbajúmọ̀ jùlọ, tí wọ́n sì kọ́kọ́ rí i nínú Ẹsẹ́ Ifá. Ó ń tẹnu mọ ìjọsìn Orí (Ori) gẹ́gẹ́ bí Oríṣà àkọ́kọ́ tí ẹnìkan ní. Ẹsẹ́ Ifá ṣàlàyé pé Orí ni ó yan ipò àti ìwà láyé fún ènìyàn kí ó tó wá, nítorí náà, kò sí ìgbàlà tàbí ìrànlọ́wọ́ tó lè ju èyí tí Orí ẹni gbà fún ni lọ.

**Ore ni igún ṣe tí igún fi pá lórí…**

Òwe yìí ń kọ́ni nípa ìwà **ìwàású** tàbí **ìdájọ́ òdodo** tí ó máa ń tẹ̀lé ìwà rere tàbí ìwà búburú. Ìtàn inú Ifá rẹ̀ sọ pé ọ̀wọ̀ tí Igún ń jẹ nínú àwọn ẹyẹ tàbí bí orí rẹ̀ ṣe pa (tí kò ní ìyẹ́) wá láti inú iṣẹ́-ìránṣẹ́ tàbí ore ńlá kan tí ó ṣe láyé tàbí nínú ìtàn àtọwọ́dọ́wọ́ kan. Ìtumọ̀ rẹ̀ ni pé: **ṣe rere, ìwọ náà yóò rí rere gbà** (ìmọ̀ àṣeyọrí/iṣẹ́).

**Ọwọ́ ọmọdé kò tó pẹpẹ tì àgbàlagbà kò wo akèrèngbè**

Ẹsẹ́ Ifá tí ó gbé òwe yìí kálẹ̀ ń kọ́ni nípa ìpínyà iṣẹ́, ọlá, àti ẹgbẹ́ láàrín àwọn ènìyàn. Ó ń fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé a ní láti fún ọmọdé láyè láti ṣe ohun tí ó tọ́ sí ikí a sì fún àgbà láyè láti ṣe tiwọn. **Bí ó ti rí** lára ọmọdé, bẹ́ẹ̀ ni yóò ṣe rí lára àgbà, gbogbo ènìyàn ni ó ní ipò àti ojúṣe wọn. Àwọn òwe Ajẹmẹ́ṣẹ-Ifá wọ̀nyí jẹ́ ẹ̀rí tó dájú pé ọgbọ́n Ifá kò dá dúró sí ẹ̀sìn lásán, ṣùgbọ́n ó ti di ara ìjìnlẹ̀ ọgbọ́n tí ó ń darí ìgbésí ayé Yorùbá. Wọ́n jẹ́ ọ̀nà láti fi tìtọ́ àti ìdánilójú sọ̀rọ̀ nítorí pé wọ́n ní àtìlẹ́yìn àgbàyé àti ìwádìí ìjìnlẹ̀ àwọn *Agbọ́gbóògùn* (Babaláwo).

**Ìtọ́kasí Ẹ̀yà Ojú-Ara Akọ àti Abo Nínú Òwe**

Lára àwọn àwòmọ́ òwe Yorùbá ní líla ọ̀rò mọ́lẹ̀ bí ó ti rí láìsẹ́nu pọ̀ ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń sọ pé 'bí a ó ti ṣe làá wí ẹnìkan kìí yan àna rẹ̀ lódì" ọ̀pọ̀ ọ̀rọ̀ ni wọ́n máa ń fi gbogbo ẹnu pé nínú òwe wọn. Èyí sì le máa da bí ọ̀rọ̀ ìsọkúnsọ létí ọ̀gbẹ̀rì tí kò bá mawo èdè nítorí pé kòsí ìsọkúsọ nínú ọ̀rọ̀ Yorùbá kódà bí ó bá ṣe ọ̀rọ̀ tí ó mẹ́nubà ẹ̀yà ojú-ara akọ tàbí abo, ọ̀rọ̀ ẹ̀fẹ̀ ni Yorùbá máa ń pè é. Bí wọ́n bá sì fi la irúfẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ ó ní ohun pàtàkì tí wọ́n fẹ fàyọ. Láwùjọ Yorùbá, lílo àwọn ọ̀rọ̀ tàbí gbólóhùn tí ó tọ́kasí ẹ̀yà ojú-ara (tí a pè ní **ọ̀rọ̀ ẹ̀fẹ̀**) nínú òwe kò wá láti sọ ìsọkúnsọ. Kàkà bẹ́ẹ̀, ó jẹ́ ọ̀nà láti; fi ọ̀rọ̀ múlẹ̀, ṣe àfàyọ ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ àti pe àkíyèsí olùgbọ́ sí**.** Àwọn òwe Yorùbá kan wà tí ó jẹ wí pé wọn máa ń ṣe àmúlò ọ̀rọ̀ ẹ̀fẹ̀ tí ó ń tọ́kasí ẹ̀yà ara bí i ojú-ara akọ ati abo. Ẹ wo àpẹẹrẹ díẹ̀:

**Kò jẹ́ kí olóbò ó rò ẹni a dó ní í kakọ**

Òwe yìí tọ́ka sí ìwà-hù àti ìdájọ́ òdodo lórí àwọn tí kò ní agbára tàbí ipò tó lágbára. Ẹni tí a dánilójú tàbí tí a ṣẹgun ni yóò ṣe ìtìjú rẹ̀ (kakọ) láìfọ́hùn. Ìfàyọ Ọgbọ́n: Má ṣe jẹ́ kí ìwọ́ tàbí agbára rẹ mú kí o gbé àwọn ẹlòmíràn lọ́jù; ẹni tí kò bá ní ipa ni yóò ru ẹrù ìtìjú náà.

**Okó tí kò le enìkan kì í fi ipá le é**

Òwe yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ohun tí kò bá ní agbára tàbí ète fúnrarẹ̀ kì í fi ipá mú ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí ìyípadà wáyé. Okó tí kò le (kò ní agbára) kò lè fi ipá ṣe iṣẹ́ tirẹ̀. Ìfàyọ Ọgbọ́n: Ìṣe tàbí ipá ìbẹ̀rẹ̀ kan gbọdọ̀ wá lára **ènìyàn fúnra rẹ̀ tàbí ipò náà fúnrarẹ̀**, kò sí ẹni tó lè fi ipá tẹ́ ọ lára láti ṣe ohun tí agbára rẹ kò gbé.

**Okó ń tókó ẹpọ̀n ń tẹ́pọ̀n awọ ọ̀kan yi ju ọ̀kan lọ**

Òwe yìí ń ṣàlàyé ìyàtọ̀ àti ìjìnnìkan nínu ipò tàbí ipa àwọn nǹkan tàbí ènìyàn méjì tí wọ́n jọra. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Okó àti Ẹpọ̀n wà ní àyíká kan náà, iṣẹ́ àti ìfarajì wọ́n yàtọ̀. Ìfàyọ

Ọgbọ́n: Kódà láàrín àwọn ẹlẹgbẹ́ tàbí àwọn tí wọ́n jọ wà ní ipò kan náà, ọlá àti ipò ẹnìkan lè ga tàbí kéré sí tìrẹ, gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ wọn ṣe yàtọ̀.

**A kì ì lóyún nínú ká fòbò tọrọ**

Òwe yìí ń tọ́ka sí òtítọ́ àti ìbáṣepọ̀ láàrín ìṣẹ̀lẹ̀ àti àyọrísí rẹ̀. Ẹ̀yà ara tí ó yẹ fún ìfẹ́ àti ìfúnni (obo) kò lè tọrọ àyọrísí tí ó ti inú rẹ̀ jáde (oyún). Ìfàyọ Ọgbọ́n: Kò yẹ kí o tọrọ ìrànlọ́wọ́ lórí ohun tí o ti ní lára tàbí tí ó ti gbà tẹ́lẹ̀ (ìmọ̀ ààbò ọrọ̀ ẹni). Tàbí pé, má ṣe fi ọwọ́ gbọn nǹkan tí o fẹ́ fúnra rẹ.

**Ẹ̀ẹ̀kan ni àtannidó ń tanni dó mọ**

Òwe yìí ń tọ́ka sí ìkìlọ̀ nípa àìlétò, àìbọwọ̀, tàbí ìwà tí kò tọ́. Ẹni tí ó bá ṣe ohun ìwàkíwà kan (tani dó), kò ní ní àyè láti ṣe é lẹ́ẹ̀kejì. Ìfàyọ Ọgbọ́n: Ọ̀kan ni àyè tí ó wà láti tọ́ ìwà rẹ lójú àwọn ènìyàn, bí o bá ti ṣe àṣìṣe kan, kò sí àyè láti rí ìgbẹ́kẹ̀lé tàbí ipò yẹn mọ́.

**Àwọn Òwe tí Orí tàbí Ẹ̀mù/ẹsẹ̀ wọn ti Kú**

Ọ̀kan pàtàkì lára àmúyẹ òwe Yorùbá ni pé apá/abala méjì ni ó máá ń ní. Èyí tí a lè pè ní orí àti ẹ̀mù tàbí orí àti ìbí. A lè pa apá/abala kan nínú òwe yìí (yálà orí tàbí ẹ̀mù/ orí tàbí ìdí) kí á fi apá kejì pamọ́ tí kò sì ní pa ìtumọ̀ rẹ̀ lára yálà láti ọ̀dọ̀ olùṣọ tàbí olùgbọ́. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé a máa ń rí àwọn òwe kan tí wọn yóò ní orí tí wọ́n kò ní ní ẹ̀mù. Apòwe lè pa orí kí ó fi ẹ̀mù rẹ̀ pamọ́. Àkíyèsí fi hàn pé, ọ̀pọ̀ òwe Yorùbá ni àwọn èwe òde òní kò mọ àpajá rẹ̀ mọ́ nítorí pé láti ìgbà láéláé ni wọ́n ti máa ń pa orí fi ẹ̀mù sílẹ̀ tàbí kí wọn ó pa ẹ̀mù kí wọn ó fi orí sílẹ̀. Irúfẹ́ àwọn òwe tí orí wọn ti kú tàbí tí ẹ̀mù wọn ti kú ni a





fẹ́ yẹ̀wò ní abala yìí. Ẹ jẹ́ kí á wo díẹ̀ lára àpẹẹrẹ àwọn òwe tí à ń pa orí tí a sì ń gbàgbé ẹ̀mù, ẹsẹ̀ tàbí ìdí rẹ̀ nínú àtẹ ìṣàlẹ̀ yìí.

| S/N | Orí Òwe | Àpajá Òwe |
|---|---|---|
| 1. | Ọ̀tọ̀tọ̀ ìyí ni àna ìgbín | Ọ̀tọ̀tọ̀ ìyí ni àna ìgbín,<br>**Ahun ko,**<br>**O kò súta,**<br>**Ìlákọ̀ kú,**<br>**O kò sọ̀fọ̀,**<br>**O wá pàdé Òkòtó lọ́nà**<br>**O wá ń fi ìkarahun rẹ̀ lu arara wọn** |
| 2. | Ó rú mi lójú àgbàlo ọ̀gànjọ́ | Ó rú mi lójú àgbàlo ọ̀gànjọ́<br>**A lé e lógún**<br>**A ṣe ènì rẹ̀ lọ́gbọ̀n,**<br>**A ṣe gbà wọn-on si rẹ̀ ní àádọ́ta** |
| 3. | Ẹni tó gbinsu méjọ tó pè é ní mẹ́wàá | Ẹni tó gbinsu méjọ tó pè é ní mẹ́wàá,<br>**Tó bá jẹ òtítọ́ tán yóò padà jẹ irọ́ mọ́-ọn** |
| 4. | A kì í ya ọmọ àlè ọ̀nà méjì | A kì í ya ọmọ àlè ọ̀nà méjì<br>**Baba ní í rújú**<br>**Ìyá kì í rújú** |
| 5. | Ó ga ò, | **Ó ga ò,**<br>**Òkú ìyá alákíá**<br>**A dì í kalẹ̀ tan ó tún ń só** |
| 6. | Ọ̀kùnrùn má mú orúkọ mi rọ̀run | Ọ̀kùnrùn má mú orúkọ mi rọ̀run,<br>**A díá fún eléèfọ̀ àwo** |

| | | |
|---|---|---|
| | | **tóní kí ló ró wò ó?** |
| 7. | Gbà nísu ni gbà lákàsù | Gbà nísu ni gbà lákàsù,<br>**Gbà lákàsù ni gbà lósù agà**<br>**Ìgba ẹnu eku ni ìgba ẹnu ọ̀fọ́n-ọ̀n** |
| 8. | Orin wo ni à á kọ sí gbẹ̀du báyìí | Orin wo ni à á kọ sí gbẹ̀du báyìí,<br>**Tayọ èrò yà wá á wò ó** |
| 9. | Ìwọ̀nba ni tanpẹ́pẹ́ ń gbìjà ẹyìn mọ, | Ìwọ̀nba ni tanpẹ́pẹ́ ń gbìjà ẹyìn mọ,<br>**Tó bá dé ibi omi gbígbóná**<br>**Kò ní dúró** |
| 10. | Àtẹ́lẹwọ́ fòde sọ̀kan | Àtẹ́lẹwọ́ fòde sọ̀kan,<br>**Àtàǹpàkò ló ya ti ẹ̀ sọ́tọ̀** |

Bákan náà, àwọn òwe kan ń bẹ tí à ń pa ẹ̀mù tàbí ìdí ṣùgbọ́n tí à ń gbàgbé orí. Ẹ jẹ́ kí á tún wo àpẹẹrẹ díẹ̀ nínú wọn nínú àtẹ ìṣàlẹ̀ yìí:

| S/N | Ẹṣẹ̀ Òwe | Àpajá Òwe |
|---|---|---|
| 1. | Ẹní yára lÒgún ó gbè | **Ààyá gbọ́n Ògúngbè gbọ́n,**<br>**Ààyá ń tiro**<br>**Ògúngbè ń bẹ̀rẹ̀**<br>Ẹní yára lògún ó gbè |
| 2. | Ẹni tó fẹ̀gúsí ṣe nánmọ̀ ni kò ṣe é re. | **Kò sí lọ́wọ́ ẹni tó jàmọ̀là tí kò sanwọ́,**<br>Ẹni tó fẹ̀gúsí ṣe nánmọ̀ ni kò ṣe é re. |
| 3. | Ẹni tó yó kì í yán | **Ẹni ebi ń pa kì í gùnfẹ̀,**<br>Ẹni tó yó kì í yán, |
| 4. | Èésú kò lérè | **Ìdá nìkó**<br>**Ìkó nìdá**<br>Èésú kò lérè |
| | | |
| 5. | Obìnrin ní í ṣekú pa Ọkùnrin | **Ìtàkùn ní í sekú pa ọ̀kẹ́rẹ́,**<br>Obìnrin ní í ṣekú pa Ọkùnrin |
| 6. | Kí là ń wá ní fùrọ̀ Obìnrin | **Bí kì í bá ṣe tọmọ,**<br>Kí là ń wá ní fùrọ̀ Obìnrin |
| 7. | Oníṣẹ́ ọdún kì í gbin Àgbọn | **Alágbàro kì í gbin ọ̀gẹ̀dẹ̀**<br>Oníṣẹ́ ọdún kì í gbin Àgbọn |
| 8. | Èjì lọ̀rẹ́ gbà | **Ọ̀rẹ́ ò gbẹlẹ̀ta**<br>Èjì lọ̀rẹ́ gbà |

| | | |
|---|---|---|
| 9. | Ẹni a dó ní í kakọ | **Kò jẹ́ kí olóbò ó rò** Ẹni a dó ní í kakọ |
| 10. | Ìsọ̀rọ̀ nìgbèsì | **Ìsúnkun símú ni ìgbétè ganngan,** Ìsọ̀rọ̀ nìgbèsì |

## Ìtúpalẹ̀ Òwe ní Ìlànà George Milner

George Milner, onímọ̀ ẹ̀dá-èdè, pin òwe kọ̀ọ̀kan sí mẹ́rin tí ó pè ní (quadripartite structure). Èyí tí ó túmọ̀ sí pé òwe ní abala mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Gẹ́gẹ́ bi a ti ṣe ṣàlàyé síwájú pé òwe Yorùbá máa ń ní orí àti ẹ̀mù/ ẹsẹ̀/ìdí. Apá/abala méjì ọ̀tọ̀tọ̀ yìí ni George Milner (1969) tún pín sí mẹ́rin. Ó pín orí òwe sí méjì, ó sì pín ẹ̀mù rẹ̀ náà sí méjì. Ìpísínsí yìí ní ó sọ pé a lè fi mọ irú iṣẹ́ tí òwe kọ̀ọ̀kan ń jẹ́ ní àwùjọ. Odù (code) tí a lè fi de ìpínsí yìí ni a pè ní òfin "Ẹja-n-bákan". Ẹ máà jẹ́ kí á gbàgbé pé "akàn" ni "ire" nígbà ti a lè pé "ẹja" ní "ibi". Ìtàn tí ó bí èyí náà wà nínú fókìlọ̀ọ̀ Yorùbá tí a ó máa mẹ́nubà nígbà mìíràn. Nínú iṣẹ́ yìí a lè pe "akan" ní "ọ̀rẹ́" nígbà ti a ó pe "ẹja" ní "ọ̀ta". Ọ̀nà tí a fi lè tètè ní òye òfin "ẹja-n-bákà" yìí ni ọ̀rọ̀ Yorùbá tí ó sọ pé "ọ̀rẹ́, ọ̀rẹ́ ẹni ọ̀rẹ́ ẹni ni", "ọ̀rẹ́ ọ̀tá ẹni, ọ̀tá ẹni ni", "ọ̀tá ọ̀tá ẹni, ọ̀rẹ́ ẹni ni", "ọ̀tá ọ̀rẹ́ ẹni, òtá eni ni". Bí a bá fi àmì + ṣe òdiwọ̀n "ire/ọ̀rẹ́" tí a fi àmì – ṣe òdiwọ̀n "ibi/ọ̀tá", a lè ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ báyìí:

**(+) x (+) = (+)** Ọ̀rẹ́ x Ọ̀rẹ́ = Ọ̀rẹ́ **"Ọ̀rẹ́, ọ̀rẹ́ ẹni ọ̀rẹ́ ẹni ni"**

**(+) x (-) = (-)** Ọ̀rẹ́ x Ọ̀tá = Ọ̀tá **"Ọ̀rẹ́ ọ̀tá ẹni, ọ̀tá ẹni ni"**

**(-) x (-) = (+)** Ọ̀tá x Ọ̀tá = Ọ̀rẹ́ **"Ọ̀tá ọ̀tá ẹni, ọ̀rẹ́ ẹni ni"**

**(-) x (+) = (-)** Ọ̀tá x Ọ̀tá = Ọ̀rẹ́ **"Ọ̀tá ọ̀tá ẹni, ọ̀rẹ́ ẹni ni"**

Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

**(a)** **(+) x (+) =** **(+)** èyí túmọ̀ sí pé orí òwe jẹ́ **akàn** tí ẹsẹ̀ rẹ̀ náà sì jẹ́ **akàn** àbáyọrí rẹ̀ náà yóò máa jẹ́ **akàn**

(+) (+)
(1) i. Ojú mẹ́rin ló ń bímọ
**(+) x (+) = (+)** **Orí**
(+) (+)
ii. Igba ojú l ó ń wò ó
**(+) x (+) = (+)** **Ẹsẹ̀**
(-) (-)
(2) i.Ìrẹ́jẹ kò sí nínú fọ́to
**(-) x (-) = (+)** **Orí**
(+) (+)
ii. Bí o bá ṣe jòkòó lo máa bá arà rẹ

**(+) x (+) = +** **Ẹsẹ̀**
(-) (-)

(3) i. Pàṣán tí a fi na ìyáálé
**(-) x (-) = (+)** **Orí**
**(+) (+)**
ii. Ǹ bẹ lókè àjà fún ìyàwó
**(+) x (+) = (+)** **Ẹsẹ̀**
**(+) (+)**

(4) i. Ọ̀tún wẹ òsì, òsì wẹ ọ̀tún
**(+) x (+) = (+)** **Orí**
**(+) (+)**
ii. Ni ọwọ́ fi í mọ́
**(+) x (+) = (+)** **Ẹsẹ̀**
**(+) (+)**

(5) i. Owú tí ìyá gbọ̀n
**(+) x (+) = (+)** **Orí**
**(+) (+)**
**ii.** Lọmọ yóò ran
**(+) x (+) = (+)** **Ẹsẹ̀**
**+ +**

**(b) (+) x (-) = (-)** èyí túmọ̀ sí pé orí òwe jẹ́ **akàn** tí ẹsẹ̀ rẹ̀ sì jẹ́ **ẹja** àbáyọrí rẹ̀ yóò máa jẹ́ **ẹja.**
(+) (+)

(1) i. Jẹ́jẹ́ ni mo jókòó
**(+) x (+) = (+)** **Orí**
(-) (+)
ii. Kì í jẹ̀bi ọ̀rọ̀
**(-) x (+) = (-)** **Ẹsẹ̀**
(-) (-)





(2) i. Ìtàkùn ní í ṣekú pa ọ̀kẹ́rẹ́,
**(-) x (-) = (+)** **Orí**
(+) (-)
ii. Obìnrin ní í ṣekú pa ọkùnrin
**(+) x (-) = (-)** **Ẹsẹ̀**
(+) (+)

(3) i. Ẹni tó bá daṣọ obìnrin bora
**(+) x (+) = (+)** **Orí**
(-) (+)
ii. Wèrèpè ló dà bora
**(-) x (+) = (-)** **Ẹsẹ́**
**(-) (-)**

(4) i. Ilé tí obìnrin bá ti ń kígbe atótó arére,
**(-) x (-) = (+)** **Orí**
(+) (-)
ii. Igi arère ní í hù níbẹ̀
**(+) x (-) = (-)** **Ẹsẹ̀**
(+) (+)

(5) i. Ẹni tí a ní ká fẹ̀yìntì ká mu dídùn ọsàn,
**(+) x (+) = (+)** **Orí**
(-) (+)
ii. Kíkan ló ń fúnni mu
**(-) x (+) = (-)** **Ẹsẹ̀**

**(c)** **(–) x (+) = (-)** èyí túmọ̀ sí pé orí òwe jẹ́ **ẹja** tí ẹsẹ̀ rẹ̀ sì jẹ́ **akàn** àbáyọrí rẹ̀ yóò máa jẹ́ **ẹja**
**(-) (+)**

(1) i. Ẹ̀gbin odò
**(-) x (+) = (-)** **Orí**
(-) (-)

ii. Ẹ̀gbin kì í pani
**(-) x (-) = (+)** **Ẹsẹ̀**

(+) (-)
(2) i. Sóńsó orí omú obìnrin a gún ni lójú ,
**(+) x (-) = (-)** **Orí**
(+) (+)
ii. Ṣìkìṣìkì rẹ̀ á díni lẹ́nu
**(+) x (+) = (+)** **Ẹsẹ̀**
(+) (-)
(3) i. Ọbẹ̀ tí kò ní èèkù
**(+) x (-) = (-)** **Orí**
(+) (+)
ii. Ló dùn uń re ìṣápá
**(+) x (+) = (+)** **Ẹsẹ̀**
(+) (-)
(4) i. Àfòmọ́ o ní gbòǹgbò,
**(+) x (-) = (-)** **Orì**
(+) (+)
ii. Gbòǹgbò igi nì í bá tan
**(+) x (+) = (+)** **Ẹsẹ̀**
(+) (-)
(5) i. Ojú ló pẹ́ sí,
**(+) x (-) = (-)** **Orì**
(+) (+)
ii. Agódóńgbó ń bọ̀ wá di kútúpà
**(+) x (+) = (+)** **Ẹsẹ̀**

**(d)** **(–) x (-) = (+)** èyí túmọ̀ sí pé orí òwe jẹ́ **ẹja** tí ẹsẹ̀ rẹ̀ sì jẹ́ **ẹja** àbáyọrí rẹ yóò máa jẹ́ **akàn**

(-) (+)
(1) i. A kì í sùn sílé ẹni
**(-) x (+) = (-)** **Orí**



Ondo Journal of Arts, Faculty of Arts, Adeyemi Federal University of Education, Ondo. Vol. 2. No. 1&2, 2026 | Òwe Yorùbá Gẹ́gẹ́ bi Ìpínṣíṣọ̀rí Ẹ̀yà Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá

(+) (-)
ii. Ká fọrùn rọ́
**(+) x (-) = (+)** **Ẹsẹ̀**
(-) (+)
(2) i. A kì í fọwọ́ ra àdému
**(-) x (+) = (-)** **Orí**
(-) (+)
ii. Kó má ní ọmọrí
**(-) x (+) = (-)** **Ẹsẹ̀**
(-) (+)
(3) i. A kì í gba àkàtà lọ́wọ́ akítì,
**(-) x (+) = (-)** **Orí**
(-) (+)
ii. A kì í gbà ilé baba ẹni lọ́wọ́ ẹni
**(-) x (+) = (-)** **Ẹsẹ̀**
(+) (-)
(4) i. Ẹni tí a ní kó kínni lẹ́yìn fẹ̀gún sọ́wọ́,
**(+) x (-) = (-)** **Orí**
(+) (-)
ii. Ẹni tí a ní kó fẹ́ni lójú ata ló fi sẹ́nu
**(+) x (-) = (+)** **Ẹsẹ̀**
(+) (-)
(5) i. Ọwọ́ tí kò sunwọ̀n
**(+) x (-) = (-)** **Orí**
(+) (-)
ii. Abẹ́ agbádá ní í gbé
**(+) x (-) = (-)** **Ẹsẹ̀**

Ondo Journal of Arts, Faculty of Arts, Adeyemi Federal University of Education, Ondo. Vol. 2. No. 1&2, 2026 | Òwe Yorùbá Gẹ́gẹ́ bi Ìpínṣíṣọ̀rí Ẹ̀yà Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá

## Ìlépa iṣẹ́ yìí

Ìwádìí yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ó yẹ kí a gbà òwe Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan pàtàkì lára ẹ̀yà lítíréṣọ̀ Yorùbá dípò ipò ohun-èèlò tí a fi ń ṣe ẹ̀ṣọ́ fún àwọn onírúurú ẹ̀yà lítíréṣọ̀ mìíràn. Iṣẹ́ yìí n jà fún ẹ̀tọ́ òwe gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùnYorùbá tí àwùjọ ti tipaṣẹ̀ àṣà àjèjì tẹ̀ mọ́ ẹrẹ̀. Ó sì tún ń tako ojú ìwòye Yúróòpù (Eurocentric literary hierarchies) tí kò bu ọlá fún àwọn ẹ̀yà lítíréṣọ̀ tí kò gùn púpọ̀. Èyí tí kò jẹ́ ki wọ́n ó kà òwe sí ipò tí ó yẹ ní àwùjọ lítíréṣọ̀

## Àwọn Ohun Pàtàkì tí Iṣẹ́ yìí Fìdí rẹ̀ Múlẹ̀

Lara àwọn ohun pàtàkì tí iṣẹ́ yìí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ ni pé àwọn onímọ̀ gbà pé òwe Yorùbá ní àwọn àmúyẹ ajẹmọ́ ewì tí ó ń tanná àṣà tí ó wà nínú iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ Yorùbá, nítorí náà bí a bá kùnnà láti kà á sí ara lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, a jẹ pé a ti fi ojú rénà ipa àti ipò pàtàkì tí àwọn ìpohùn méjèèjì yìí dìmú nínú àṣà àti ìgbésí ayé àwùjọ Yorùbá. Nítorí náà, àwọn ìdí tí ó fi yẹ kí a to òwe àti àlọ́ àpamọ̀ sí abẹ́ ìpínsísọ̀rí ewì alohùn Yorùbá nìwọ̀nyí:

### Ìwúlò Àṣà àti Ọgbọ́n

Òwe jẹ́ àwọn ibi ìpamọ́ ọgbọ́n, ìmọ̀, ìwà ọmọlúwàbí, àti àwọn ìlànà àwùjọ, wọ́n sì máa ń gbé ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò Yorùbá jáde gẹ́gẹ́ bí àwọn ewì alohùn yòókù. Iṣe pàtàkì tí à ń fi òwe ṣe ni àwùjọ kọjá èrònjà fún ewì alohùn ajẹmáyẹyẹ àti ajẹmọ́rìṣà gẹ́gẹ́ bi èrò Rájí, aayr (2009).

### Òdiwọ̀n Gígùn

Bí a bá fi òdiwọ̀n gígùn wò ó, a lè ka òwe kún ìpínsíṣọ̀rí



lítíréṣọ̀ alohùn ajẹméwì. Nítorí pé ìlà ṣẹ́kí-ṣẹ́kí ti ẹ̀yà lítíréṣọ̀ yíì wà ní ewì náà wà, o si náà sì kún fún ẹ̀dọ̀ki èdè gẹ́gẹ́ bí ewì.

### Fífi Ọnà-èdè ya Àwòrán-inú

Bí a bá ní kí á wo bí ọnà-èdè àti ìlò-èdè ṣe máa ń kún inú ewì alohùn fọ́fọ́, a lè tọ́ka sí i pé òwe náa jẹ́ ẹ̀yà àròfọ̀ tí ó máa ń kún fún onírúurú ọnà-èdè, èyí tí a fi lè tò wọ́n mọ́ ewì alohùn Yorùbá. Bí àpẹẹrẹ àfiwé jẹ́ ọ̀kan lára ọnà-èdè tó gbé àlọ́ àpamọ̀ ró.

### Àgbálọgbábọ̀

A ti wo àpèjúwe tí àwọn onímọ̀ fún àlọ́ àpamọ̀ àti òwe nínú iṣẹ́ yìí. Akíyèsí fi hàn pé ojú tí àwọn kan fi wo òwe Yorùbá gẹ́gẹ́ bi ìtọ́ṣẹ ọ̀rọ̀ lásán. Bóyá nítorí pé ìṣàmúlò rẹ̀ a máa hànde nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀yà ìpohùn yòókù ní kò jẹ́ kí wọn ó fi tò ó sí àgbọn lítíréṣọ̀ alohùn kan pàtó. Ìwádìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìpìlẹ̀ fún gbogbo ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn yòókù ni òwe jẹ́. Àtipé ọ̀pọ̀ òwe Yorùbá ni ó jẹ́ ẹ̀yà ẹsẹ-Ifá tó jẹ́ pé bí a bá pa òwe kan, a kàn nílò láti fi a dífá fún kún un ni láti di ẹsẹ Ifá. Nítorí náà, àwíjàre iṣẹ́ yìí ni pé ẹ̀yà ewì alohùn Yorùbá ni òwe Yorùbá jẹ́. Àwọn ẹ̀rí tí a gbé kalẹ̀ nínú ìwádìí yìí jẹ́rìí sí ipò títún tí ó yẹ kí á ka òwe sí gẹ́gẹ́ bí àwọn ìpínṣíṣọ̀rí pàtàkì nínú lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá.

Àbájáde ìwádìí yìí fihàn gbangba pé, nínú ìpínsíṣọ̀rí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, òwe kò ṣeé fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn. Ó fihàn pé bí a bá mú òwe kúrò nínú ewì alohùn, ewì náà yóò di 'asán', ṣùgbọ́n òwe fúnra rẹ̀ ní ìhun (structure) tó kún láti jẹ́ iṣẹ́-onà lítíréṣọ̀ tó lè dá dúró gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà (genre) kan.

Ondo Journal of Arts, Faculty of Arts, Adeyemi Federal University of Education, Ondo. Vol. 2. No. 1&2, 2026 | Òwe Yorùbá Gẹ́gẹ́ bi Ìpínṣíṣọ̀rí Ẹ̀yà Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá

**Ìwé Ìtọkasí**

Abímbọ̀lá, W. (2006). *Ìjìnlẹ̀ ohùn ẹnu Ifá*. University Press Plc.

Àjàyí, B. (2002). *Ìtùpàlẹ́ àlọ́ àpamọ̀ Yorùbá*. Shebiotimo Publication.

Enges, & A.-L. Siikala (Eds.), *Telling, remembering, interpreting, guessing: A Festschrift for Prof. Annikki Kaivola-Bregenhøj on her 60th birthday, 1st February 1999* (pp. 246–256). Suomen Kansantietouden Tutkijain Seura.

Dilthey, W. (1883). *Introduction to the human sciences* (Einleitung in die Geisteswissenschaften).

Folórunsọ́, A. O. (2010). Reclassifying "minor" Yoruba genres: A case for proverbs and riddles. *Oral Tradition*, *25*(2), 201–220.

Gadamer, H.-G. (1989). *Truth and method* (J. Weinsheimer & D. G. Marshall, Trans.). Continuum.

Milner, G. B. (1969). Quadripartite structures. *Proverbium*, *14*, 379–383.

Olátúnjí, O. O. (1984). *Features of Yorùbá oral poetry*. University Press Ltd..

Ọ̀pẹ́fèyítìmí, A. (1997). *Tíọ́rì àti ìsọwọ́lò-èdè*. Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press.

Rájí, S.M. Ayyr (2009). *Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ewì alohùn Yorùbá*. Alafas Nigeria Company.